# FIRE-FIRE INTERNATIONAL EVANGELICAL CHURCH

**IKONI NI BIBELI**

**IGBEYAWO ATI AJAGA INU RE**

***IBI KIKA:* 1KORNT*. 7:25-40 ESE AKOSOROI: 1KORT. 7:27-28 ORIN AJUMOKO: __***

***Akosori:*** *A ti de o mo aya ri bi? mase wa ona lati tu kuro. A ti tu o kuro lowo aya bi?. mase wa aya ni. Sugbon bi iwo ba si gbeyawo, iwo ko dese: bi a ba si gbe wundia ni iyawo, on ko dese. Sugbon iru awon wonni yio ni wahala nipa ti ara: sugbon mo da nyin si.*

## *Oro akoso*

Ni ibi ni Paulu ti tun tesiwaju Lati dahun ibere ti awon ijo Korinti bi lati pase iwe ti won ko si. Nibi ni o ti so pe kii se ewu lati gbeyawo, nigbati eniyan bati mo pe, oun koni ebun imara-duro. Sugbon o mu ki o ye wa iru ajaga ti awon to ba gbeyawo ki orun bo. Beni o soro nipa iyato towa laarin obinrin ti a gbe niyawo ati wundia. Lopin re ni o ti wa fun awon to je opo ni imoran nipa iriri emi toni. E jeki a se awa jinle ikoni yii labala ona meta yii.

- **AJAGA OJUSE TOWA NINU IGBEYAWO**
- **ALAKALE ATI ALAYE NIPA IYATO TOWA LAARIN OBINRIN TI A GBE NIYAWO ATI WUNDIA**
- **AMORAN PAULU FAWON TOJE OPO NIPA ORO IGBEYAWO**

### AJAGA OJUSE TOWA NINU IGBEYAWO
### I KORINTI 7:25-31

***Ni ese 25-26***

Ni ibi wa ni Paulu ti ndahun ibere ti won bi nipa enito je wundia ti kii ti se igbeyawo. Won bere wipe se ole se igbeyawo? Paulu dahun ibere yii pe, ko si ase wipe keniyan mase igbeyawo latodo Oluwa. Sugbon niti oun Paulu, gegebi aanu ti Olorun fifun oun lati je olododo ati lati ni ebun imara-duro, o ni gegebi awon nkan bi inunibini atawon ewu ti awon nla koja gegebi Kristeni ni iran igba naa, o ni oun ro pe o dara lati wa be laise igbeyawo ati pelu nitori awon eniyan ati akolekan ti igbeyawo ni ninu, pelu awon ojuse to pondan-dan funni lati se ninu igbeyawo

***Ni ese 27-28***

Ni ibi ni ati wa nso fun wa pe, boya awa tii se igbeyawo, kii se ese, beni a kosi gbodo tu ka nitori igbagbo ti a gba, a ni lati maa ba lo pelu jije olooto si ara eni ni. Bi o basi sepe, awa koiti se igbeyawo, ohun ti a nso fun wa nipe, ka maase se wari-wari wonu igbeyawo, ki a maa kanju wonu re, nitori igbeyawo ni ajaga ojuse ninu, to si yeki eniti yoo base mura fun.

Nitori a nso fun wa wipe, bi awa bari wipe gegebi okunrin tabi obinrin pe a ko le dara duro titi, kii se ese lati gbeyawo, eto Olorun fun wa lori iru oran be ni. Ohun kan ni pe, a ni lo lati fara bale mo ife Olorun lori iru eniti oye fun wa lati fe, beni kasi fara bale seto to ye fun igbeyawo. Nitori igbeyawo ni awon ojuse ninu fun okunrin ati fun obinrin eyi ni a pe ni ajaga ojuse, kii se ajaga ogun. Ajaga ojuse rere ni. Sugbon bi eniyan ko ba seto, fun o le pa irin-ajo igbagbo eniyan lara. Sugbon bi eniyan ko ba se igbeyawo koni niriri iru ajaga be.

***Ni ese 29-31***

Ni ibi ni Paulu ti wa npe wa si akiyesi idi to fi nso ohun ti nso yii, beni o si nse ikilo. Idi nipe o ti ni igbati alo lori ile aye yii, igba wa ko lo titi nitori naa akoko to kere ni o ku lati fi sise fun Oluwa. Nipa be, eniti o ba ti se igbeyawo ni lati ri wipe oun gba oore-ofe lati wa ni ominira si Oluwa lati le wulo fun ise re, ki ajaga igbeyawo maa ba di lowo. Beni a ko gbodo jeki igbadun tabi idojuko aye yawa kuro ninu sise ise fun Oluwa.

Beni a nso fun gbogbo awon ti a ni anfani si ***oro aye, ola aye***, gbodo mo pe anfani la fun wa, a kosi gbodo silo, agbodo lo fun itesiwaju ife Olorun lati fi fe ijoba re loju lori ile aye. Nitori aye ti a wa yii nlo sopin lojokan. Kosito di akoko, ati nigbati a wa nibe, ki a lo ohun ti a ni botiye. Enito si ndojuko nkan ki o mase jeki o ya oun kuro ninu ife Oluwa.

## ALAKALE ATI ALAYE NIPA IYATO TOWA LAARIN OBINRIN TI A GBE NIYAWO ATI WUNDIA

## I KORINTI 7:32-35

***Ni ese 32-33***

Ni ibi ni Paulu ti nso fun wa ohun ti nso ni pato wipe, oun ko fe ka kun fun aniyan ati akolekan ni. Pe nitori eniti ko ba se igbeyawo, ko ni ni anfani beni ko ni lomo ti yoo maa bere nkan lowo re, beni ko ni ni oko tabi aya ti yoo maa wo loju, nipa be. Alo gbogbo akoko re fun ati se ife ati ise Oluwa, ati bi yoo se maa wu Oluwa. Sugbon eniti o ti se igbeyawo. Ko le se be dara-dara nitori yoo ni akoko ti yoo firo ti enikeji re, ti omo ati tawon Anan. Nipa be koni je gbogbo akoko re, ni yoo le lo fun Oluwa tan, yoo ni akoko ti yoo maa lo fun ati se ojuse to pon dan-dan fun ninu igbeyawo ati bi yoo ti sele maa wu enikeji re. Nipa be ohun to nife si a pin si ona meji, beni bi yoo ti maa lo ohun to ni naa a pin sona meji.

***Ni ese 34-35***

Ni ibi ni Paulu kuku ti wa nso nipa iyato to wa laarin enito ti se igbeyawo ati eniti ko mon-mon se igbeyawo o ni fun apere obinrin ti ko se igbeyawo ti kosi ko aye okunrin lekan, a maa pongbe fun bi yoo se maa wu Oluwa, a tera mo awon ise isin re niwaju Oluwa ninu ohun gbogbo sugbon fun eniti oba ti se igbeyawo, o ti di dandan fun lati maa ro bi yoo se toju oko, omo ile ati pelu yoo maa kiyesi awon ohun ti oko re fe atawon ohun ti ko fe. Beni okunrin naa, a maa lepa bi yoo se te aya re lorun, bi yoo se pese fun idile re dara-dara. Awon nkan yii ni ajaga inu igbeyawo, o si je ajaga ojuse rere kii se ajaga ogun.
Ni ibi naa ni Paulu ti nso fun wape, oun nso eyi lati ran wa lowo ni, ki a le mo eyi ti a se, ati bi a se gbaradi si lati se, ko maa di pe a rolu tan a wa ndara wa lebi. O ni kii se wipe oun ni kamaa se igbeyawo, sugbon kale mo ojuse towa nibe, ti a fi seto toye fun ti ko fini di ati sefe ati ise Oluwa tabi ise isin wa si Oluwa lowo.

***Ni ese 36-38***

Ni Paulu ti nso asoye fun wa pe, bi enikeni ba ri pe, oun kole dara duro, tori wipe a ko fifun oun lati wa laise igbeyawo, o dara ko lo se igbeyawo pelu eniti Oluwa yoo yan fun. Kii se ese fun lati se igbeyawo rara. Olorun lo seto re. Be sini bi eniyan bani wipe, a fifun oun lati wa be laise igbeyawo, to si pinnu be funrare lati mase, ipinnu rere lose. Sugbon Olorun ko pase re fun enikeni ***(ifara eni rubo ninu igbagbo lati le sin Oluwa tayo ni)***. Nitori naa, eniti o se igbeyawo se rere o gba bi ***(60-85 percent).*** Beni eniti o ko lati see, laise pe ko pe lara, laise ogun, sugbon to pinnu lati duro, o gba ***(90-99 percent )***. O gba dara dara julo. Nitori naa, o wa nipa wa lati yan.

## AMORAN PAULU FAWON TOJE OPO NIPA ORO IGBEYAWO

## I KORINTI 7:39-40

Ni ibi ni Paulu ti wan fun awon to je opo nimoran lori oro igbeyawo. O ni a fi ofin de oko ati aya papo niwon igbati awon mejeeji bati se igbeyawo ti won sijo wa laaye sugbon bi ikan ba sun ninu won. Ekeji ti wa ni ominira lati lo ni oko bi o ba fe, ninu ife Oluwa. Eyi nipe yoo fara bale ki Oluwa yan fun, koni je pe yoo lo gba oko oloko tabi aya alaya. Nibi naa ni Paulu ti so nipa ti ara re pelu awon oro toti nso bo, wipe bi o ba se ti oun ni, gege bi oore-ofe ti a fun oun, oun yoo wa be laini aya mo. O ni iru eniti o ba wabe yoo layo pupo julo, a bo kuro ninu aniyan topo, aniyan re a mo niwon, yoo sile fi ara re fun Oluwa gidi-gidi

Nipari, Olorun ko ni keniyan mase igbeyawo sugbon bi eniyan bale se, latari kole sin Oluwa dara-dara. Yoo gba ade ogo re. Beeni Olorun lo seto igbeyawo fun eniyan gbogbo fun awon idi to po, fun ire ati ere eniyan. Awa ni a mo eyiti a se, ti a fi le se ise isin fun Oluwa laisi idiwo.